Ogun Ita'ja

E Polowo oja yin sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe, Kia L'oja o ta.

ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

Akiyesi Pataki

A fi iwe yi se ikede si awon Asoju iwe irohin Eleti Ofe kakiri agbaiye wipe, enikeni ti ko ba fi owo ti o ti je ranse si wa ,ao pe leio, ako si ni fi iwe irohin ranse si enibe mo.

VOL. XI No. 611. LAGOS, SATURDAY, FEBRUARY 14 — FEB. 20, 1959 KOBO MEJI (2d).

# Omo'ba'binrin Margaret Yio Kara-kun Ayeye Ominira Wa Ni 1960

Ọmọba obinrin ti iṣe aburo ọba obinrin ilu Oyinbo Gesi ti orukọ rẹ njẹ Princess Margaret ni Olotu ijọba Apapọṣe kede ninu ile igbimọ nla ti ilu Eko wipe Alaiyeluwa Ọba obinrin ti gba ipe awọn Alakoso ijọba Nigeria fun Ọmọba obinrin Margaret na lati wa ba wa kara-kun arisiki ayẹyẹ ọjọ ti a o gba ominira nilẹ Nigeria gẹgẹbi aṣoju ọba ilu Oyinbo.



Ọmọba yi koiti de ilẹ Nigeria ri, bi a ba mu ti ilu Kano to de bi ẹniti ko de'bẹ kuro ninu ọdun 1959. Ninu oṣu September ati October ọdun 1959 ni Ọmọba Margaret bẹ awọn ilu bi Kenya, Mauritius, Zanziba, ati Tangayika wo.

Ọmo'ba Margaret tun bẹ ilu Wesingisi wo ninu ọdun 1955 ati 1958. Eyiti ko-ni-gbagbe ni abẹwo ti Ọba Alaiyeluw ati Ọlọlajulọ ọkọ rẹ wa bẹ ilẹ Nigeria wo ni 26th January si 16th February 1956.

O da wa loju wipe gbogbo ilẹ Nigeria ni yio tẹwọ ifẹ ailabawọn gba ọmọba na lalejo gẹgẹbi iṣe ati iṣedalẹ awa enia ilẹ Nigeria.

## Olorun Se Eda Enia Ju Gbogbo Eda Yoku Lo

Nigbati Olodumare ṣe ẹda ile aiye pari tan, orun nla, o si nwọ, oṣupa ntanna irawọ ntan odonsan lọ jẹjẹ awọn eiyẹ nkorin lori awọn ẹka igi ko si eyikeyi ti o ti mọ wipe Olodumare ṣe ẹda ohun kan ti o njẹ ile aiye.

Olodumare pe gbogbo awọn Angẹli Rawania ati awọn Alijannu jọ o wi fun wọn pe ao ṣe eda enia. Awọn Irunmọlẹ nwọnyi bere wipe nibo ni awọn enia na yio wa ti nwọn o ma gbe? O si dahun pe ninu ile aiye ni. Nwọn bere wipe nibo ni aiye na wa?

Nigbayi ni Ọlọrun ṣilẹkun ọrun silẹ pe ki nwọn lọ rin ilẹ aiye na wo, gbogbo nwọn folọ sile aiye nwọn si nwo gbogbo nkan ti Ọlọrun da pẹlu iyanu. Bi nwọn ti nwo ile aiye lọ ni nwọn de ẹgbẹ oke apata nla kan, nwọn mi i ko mi. Nwọn wa bere l wọ Olodumare wipe :-

Awa ri apata nlanla kan eyiti o ṣe eda re sile aiye, njẹ ẹda kan ha wa ti o le lagbara ju apata na lọ bi ? Olodumare dahun wipe bẹni o wa. Kini orukọ eda na ? O ni Irin lagbara ju apata lọ.

Nwọn tun bere pe kini lagbara ju irin lọ? Olodumare dahun wipe bẹni o wa. Kini oruko eda na ? O ni Ina lagbara ju irin lọ

Nwọn tun bere pe, kini lagbara ju Ina lọ, ? Olodumare ni o dahun pe Omi lagbara ju ina lọ. Kini lagbara ju omi lọ o dahun pe Efufu lagbara ju omi lọ.

(Koiti pari)

No 26

FEDERAL ELECTION, 1959 -

Lagos Registration

All registration offices in the three Lagos Constituencies will, commencing with Saturday 14th February, open on Saturdays at 2 p. m. and not 3 30 p. m. as already published. On Mondays to Fridays the Registration offices will be open from 3. 30 p. m. to 6. 30 p.m.

Registration Application Forms may be obtained from any registration office.

REGISTRATION OFFICER,
LAGOS CONSTITUENCIES

# Sardauna Tajo De



Sir Alhaji Ahmadu Bello, Oloye Sardauna Ṣokoto ti o si tun jẹ aṣiwaju awọn oṣelu ilẹ Hausa, (Premier) ilẹ Oke - Ọya, ẹniti o ti ba ọkọ ofurufu lọ silu oyinbo lati lọ gba aṣẹ lori oye ti ọba ilu oyinbo, Queen Elizabeth Keji, fi ta a lọrẹ, ti pada de silu rẹ, o si ti mba iṣẹ rẹ niṣo.

## Itan Kongbo-Kongba Ara Re Lo Nse Nika

(Apa III)

Lati Ọwọ Ẹṣo

Kongbọ da oko yi lọ rẹpẹtẹ, ẹigun rẹ to busọ kan, ilẹ rẹ si to busọ kan Asiko na lẹ asiko ti ojo ṣẹ ... ofẹ fi ẹsu balẹ. Kongbọ ro ninu ara rẹ pe, asiko ti a ogbin iṣu ti kọja, asiko agbado niyi, ni Kongbọ ba pada lọ sile.

O wọn panu agbado meji nigbati ile mọ, o gbe agbado na o si kọri si ọna oko abami na. Nigbati o de ibẹ, o joko woye lọ su-u wipe, Hẹn! njẹ emi na, ni Ọlọrun ṣe nkan fun bayi? o jẹ iṣu o mumi si lo ba bu die ninu agbado o bẹrẹ si ri mọle.

Bi o ti ri bi ẹba mefa bẹni o tun gbọ ohun Onigbo lati ọna jinjin wa wipe iwọ tani yẹn? o si dahun wipe emi Kongbọ kini o nṣe? mo ngbin agbado njẹ Jọnmọ ẹ ba gbin i. Bẹni Kongbọ ri ti panu agbado rẹ dide nilẹ ti o si nlọ siwa sẹhin titi ti ofifo panu fi pada wa. Iru ewo niyi gẹgẹbi a ti sọ fun nyin pe Olorikunkun ni Kongbọ sibẹ ko dẹhin lẹhin oko yi.

Lọjọ keta gbogbo awọn agbado na lo suyọ winrin, inu Kongbọ dun, nigbati yio fi to oṣu meta gbogbo agbado na ti pọnmọ ṣọrọ-ṣọrọ. Ọfọ kan wa ṣẹ Kongbọ o si ni lati lo sibi oku na. Nigbati Kongbo yio si jade o pe iyawo rẹ, o kilọ fun pe 'on nlọ si abule keji, nitorina ko gbọdọ de oko on titi on yio fi pad de, ni Kongbo ba lo sibi oku.

Ni ojo keji ti Kongbo lo tan ni omo rẹ nsokun asundabo nitori a ti jẹ agbado o si wa nṣebi eyiti yio daku ni iya omo na ba ṣare lo ya agbado kan ninu oko baba rẹ. B' o ti de ibe ti o ya agbado kan, bẹni Onigbo bere pe iwọ tani yẹn? o ni emi iyawo Kongbo ni kilo nṣe? mo nyagbado ni Jọnmo ẹ ba ya a, ni gbogbo agbado ba ṣubu lulẹ.

Nigbati Kongbọ de ti o ri ohun ti o ṣelẹ ninu oko rẹ o lọ pe iyawo rẹ wa wo, o si ko ẹgba bo fun on ti o ṣe Onigbo bere pe iwọ tani yẹn? emi Kongbo ni kilo nṣe? Mo nna iyawo mi ni Jonmọ e ba na ni nwọn ba na iyawo na pa. Nigbati Kongbo ri ohun ti o ṣelẹ, o fi ọwọ gba ara rẹ lori wipe ye, ye, ye, ori on buru Onigbo tun bere pe iwọ tani yẹn emi Kongbo ni kilo nṣe mo nfi ọwọ gba ara mi lori ni Jọnmọ ẹ ba a gba ni nwọn ba gba ori Kongbọ ni agbafọ. Eyi nigbẹhin Kongbọ-kongba.

---

**E MA KA IWE IROHIN ELETI - OFE L'ỌSỌSẸ OKUN FUN IROHIN ALADUN**

---

# Eto Fun Awon Ti Nlo Si Mecca

Iṣẹ Igbimọ ti a yan lati mojuto awọn ti nlọ si Mecca lati Iwọ Orun Naijiria ni lati ṣe eto ọkọ ati ibugbe fun wọn.

Igbimọ yi ngbero bi o ba seṣe lati ran awọn ti nlọ si Mecca ni Ipinlẹ Iwọ Orun lọwọ nipa gbigba owo lọwọ wọn lẹkan fun irin-ajo wọn lati san owo fun iwe ti wọn nilati mu dani, owo ti Ijọba Saudi Arabia ma gba ati fun awọn nkan imiran gẹgẹbi owo ile ni ilu Saudi Arabia. Nigbana Igbimọ a le ṣe eto fun awọn ti nlọ si Mecca.

Ki a to le ṣe eyi o yẹ ki Igbimọ mọ iye enia ti nwọn fẹ lọ si Mecca ni ọdun yi, ti nwọn si fẹ lo anfani ti Igbimọ fẹ lati fun wọn.

A pe irufẹ awọn enia bẹ ki nwọn kọ iwe nisiyi si akọwe Igbimọ yi :-

The Secretary,
Pilgrims Welfare Board,
c/o Premier's Office,
Ibadan.

Nwọn nilati sọ fun akọwe pe nwọn ngbero lati lọ si Mecca lọdun yi, nwọn a tun sọ bi ọkọ ofurufu tabi ọkọ ilẹ ni nwọn fẹ lati wọ. Nwọn a si tun sọ bi nwọn ba ma mu lọ ninu ẹbi wọn. Iwe awọn ti ngbero ati lọ si Mecca nilati de ọdọ akọwe Igbimọ ni ọjọ kẹdogun oṣu yi tabi ki o to tobẹ.

# Electricity Corporation Of Nigeria

## Invitation To Tender

SAPELE—WARRI 33 K.V. TRANSMISSION LINE

Tenders are invited from responsible Contractors for the survey, design, supply and erection of a 33,000 Volts Single Circuit Transmission Line between Sapele and Warri.

Tender documents comprising Tender, Form of Contract, Specification of the Contract, etc., may be obtained on payment of a deposit of £5 from :-

The Secretary,
Electricity Corporation of Nigeria,
Electricity Headquarters,
Private Mail Bag 2030,
Broad Street, Lagos.

Each tender must be enclosed in a sealed envelope endorsed "Confidential - Tender for Sapele-Warri 33 kv Line" and must be received at the Office of the Secretary not later than noon 7th March, 1959. Tenders received in any other manner will not be considered.

It is essential that the Tendering Contractor shall be in a position to produce evidence of having successfully undertaken previous contracts of a similar nature.

On receipt of a Bona Fide Tender, the deposit of £5 will be refunded. The Electricity Corporation of Nigeria does not undertake to accept the lowest or any tender. Further information concerning this contract may be obtained on application to the Chief Electrical Engineer at this Headquarters.

**Arthur Faul.**
SECRETARY TO THE CORPORATION


## ỌRỌ OLOYE OKOTIE-EBOH JỌNI LOJU



EKO. Oloye Festus Okotie-Eboh

lo sọrọ yi ninu ile igbimọ nilu Eko wipe awa, gẹgẹbi orilẹ ede ilẹ Nigeria yio sa agbara wa lati ri daju wipe lẹhin ti a ba gba ominira tan, ki owo wa tunbọ le ma po si lati le ma fi se itoju ohunkohun ti o ba de fun itosiwaju ilẹ wa ati fun alafia awon enia ilẹ Nigeria ati lati fi dabobo ilu wa, nigbati ilẹ wa ba di okan ninu awon orilẹ-ede gbogbo agbaiye ati okan ninu awon orilẹ ede ti o ti bo ajaga silẹ ninu igbekun.

## Owe Yoruba

Nigbati ẹ npa ẹwurẹ nigbati ẹ npa agutan awa ha dele nyin jẹun ri ?.

## Ijọgbọn Be Sile Ni Ajase Nile Dahomi

PORTONOVO. Ijọgbọn kan bẹ silẹ ni Ajaṣẹ, nigbati awọn Faranse ṣi ile igbimọ (Assembly) silẹ ti nwọn si rauṣẹ pe awọn ijimi enia nilẹ na fun apero nipa gẹgẹbi nwọn o ti ṣe fun awọn ara ilu na ni Ominira.

A gbọ wipe awọn apakan ninu awọn enia na dahun pe, awọn ti nwọn fẹ joko ṣe igbimọ yẹn, awọn ko ni gba ki nwọn tun ṣe igbimọ le wọn lori lodun ni, nitori asiko ti to ti a ni lati yan enia titun sinu igbimọ na.

Bi awọn igbimọ ti nwọ inu ile igbimọ beni awọn alatako nwọnyi pẹ'u si lọ joko sori aga igbimọ. Bi nwọn ti nsọrọ lọ, bẹni awọn alatako npariwo pe, ako fẹ nyin mọ, ẹ jawọ kuro ninu apọn ti ko yọ.

Nwọn sọ pe, iṣẹ ti awọn igbimọ jẹ ninu igbimọ yi, ẹnikan ko ran wọn. Nigbati ijọgbọn pọ tan, Ijọba Faranse ni ki gbogbo wọn jade, nwọn si nlọ tikọtikọ ni awọn ọlọpa ba lo etu apanilẹkun (Tea. Gas).

Ọrọ na wa di bi o ko lọ yago fun mi ni awọn ọlọpa ba tẹ igi bọwọn lara tobẹ ti awọn enia mẹdogun fi fara ṣeṣe.

## Itan Elegbeje Ado

Lati ọwọ
Y. Ade Buraimọh

Gbogbo ẹsẹ awọn ara ilu ti pe si afin, wọn nreti Ọdẹ Elegbeje-ado lati ri gẹgẹbi ọba yio ti ṣe da ni Ọla, laipẹ rẹ ni Ọdẹ-Elegbeje-ado de gbogbo awọn ara ilu adigbo lu arawọn lati fi ojn kan. Ọdẹ-Elegbeje-ado de ọdọ ọba o ki ọba, Kabiyesi, k'ade ko pẹ lori ki bata pẹ lesẹ, emi oye aguo, o, ọba si ti fi aye ijoko rẹ silẹ ki o to de, bẹni Elegbeje ado joko sori aga, o wa wo gbogbo ori enia lọ, o to Ẹgbẹrun mẹdọgbọn (25,000 peoples).

ỌBA BẸRẸ ỌRỌ SISỌ

Keese eese o, keese o tọmọde t'agba lọkunrin l'obinrin, ki ẹ dakẹ jẹẹ kiẹ maṣe wu ikọ ẹniti ikọ ba ngbọn kio bọ si ita fun wa diẹ ẹniti ọmọ rẹ ba nsunkun, kio fi ọyan si lẹnu, tabi bẹkọ, kio yẹra fun wa diẹ Ohun ti a pe yin si ni oni nipe kia fi han yin gbangba kiẹ mọ ẹni ti o ko yin yọ kuro lọwọ ewu awọn ọlọṣa to wọ igboro ilu wa.

Ẹni ti o ṣe agbara na ni yi ọpọ enia mọ dada, ọpọ enia ko si mọ rara ati ẹniti o mọ ati ẹniti ko mọ, emi ọba tiẹ fi jẹ alaṣẹ ilu yi wa fẹ lati fi han yin ki nsi da ni ọla ti o tọ si eyi ti o yẹ pẹlu. Njẹ ẹnyin enia mi gba mi laye tabi fun mi ni aṣẹ lati da ọkunrin yi ni Ọla bi? gbogbo awon enia l'okunrin l'obinrin si dahun pe a fun ẹ ni aṣẹ ki o da ohun ini rẹ si meji ki o fun ni apa kan lowu wa papa

Gbigbọ ti ọba gbọ eyi inu rẹ dun ju bi o ti yẹ lọ ohun ti o mu inu rẹ dun ni pe asiko ti on joye tabi alaṣẹ ilu ko baje ni ori on ogo nlala si ni o ṣe fun on.

Ọba wa wọ ile rẹ o fun Elegbeje-ado ni ewu etu mẹrin, ati fila rẹ ati ṣiki alagba, pelu ṣokoto ki o ma fi lo, lẹhin eleyi o tun wa fun ni ẹṣin kan pẹlu ẹṣọ rẹ ati aga ti ide kun ara rẹ. ati Iyawo kan kio ma se onjẹ fun ati bio ti to ati bi o ti ye pẹlu gbogbo awọn ara ilu wa dupẹ lopọlọpọ lọwọ Ọba fun ohun ẹyẹ ti o se fun Olusegun awọn ọlọṣa igboro ilu.

ELEGBEJE-ADO DUPẸ

Ọdẹ Elegbeje-ado dupẹ lọwọ awọn ara ilu ati ọba pẹlu awọn Ijoye rẹ, on ti mo ri loni yi o jẹ iyalẹnu fun mi gidigidi, ki li o mu jẹ iyalẹnu na emi ti moduro siwaju yin loni yi ki iṣe oloye ilu beni ki iṣe ọlọla ilu ṣugbọn eyẹ tiẹ se fun mi loni yi, mo dupẹ pupọ lọwọ yin.

(Koiti pari)


Kere o !

Ati ni orisirisi ogun German to ṣẹṣẹ dẹ, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ ki o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS
MEDICINE STORES
, Egerton Road Lagos

# ELETI - OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS    CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos.    "ELETI - OFE LAGOS"

P. O Box 467    Phone 23370

VOL. XI. NO. 611. SATURDAY FEB. 14 - FEB. 20, 1959


## Ibinu Koda Nkan

Suru ni baba iwa, ni ọrọ owe awọn Yoruba mọni mọni ti o kun fun fun ọgbọn ati lakaye gidigidi ni a fi ṣe akọle wosika wa ọsẹ yi fun ẹnyin ọkawe wa gẹgẹbi aṣayan ọrọ wa ti a fi ma ngba arawa niyanju tabi ṣi arawa leti sinu iwe irohin wa oloyinmọmọ yi lọsọsẹ.

Kọsi ohun ti enia leṣe ni aṣeyọri si rere nile aiye wa yi laiko fi suru kun nkan na, bi enia ba ni obinrin ti ko ba ni suru, asan ni bẹnani obinrin si ọkọ rẹ ati paapa ko tilẹ si ohun ti enia le ni laini suru ti ohun na le ba oluwarẹ di alẹ. Bi enia jẹ onibinu pupọ, eyiti nwọn npe ni inu fufu, jamba, ijọgbọn ati wahala ko jinna si ẹnibẹ.

Eyi l'o mu awọn ọmọ Alahusa p'owe wipe "Ankari mọgamal duniyan, ti itumọ re ni ede Yoruba jẹ "Suru l'ogun aiye" njẹ ko ha yẹ ki enikẹni l'okunrin, l'obinrin, l'ọmọde ati agba ti o ba fẹ gbe ile aiye yi ni suru ki oluwarẹ le ni igbadun ati ifọkanbalẹ.

Nitoripe n'Ilu Eko tiwa yi bi enia ko ba ni suru, ararẹ ni yio jẹ niya gẹgẹbi ọrọ awọn enia wa ara ilẹ oke to wipe "Enia ti o nr'Eko ki o b'omi suru mu, Kurumọ a na'ni Aganyin a na'ni, Adamu orisa a pa oluwarẹ l'agbọn.

Onisuru l'o nṣ'ọkọ ọmọ Alahusa.


## Imoran Fun Enyin Abiyamo

**Enyin Abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRẸLA o dara pupọ fun awon ọmọde.**

Ama je ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun inu, ikọ ati orisirisi arun miran ti o ma mba ọmọ ja ni asiko ehin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti won si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Ṣile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemists)
10, VICTORIA STREET, LAGOS.


## Awolowo Fe Ko Ilewe Ofe Si Ie Awon Ibo.



**EKO.** Ninu ipade ti awọn ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe lọjọ Saturday 7th nṣọ Feb 1959, sọ wipe ẹgbẹ Afẹnifẹre yio kọ ilẹ ẹkọ University kan silu Eko, yio tun da ilewe ọfẹ silẹ ni agbẹgbe ilẹ Ibo.

Awolowo so wipe awon ara Ila-orun ko ri iṣẹ ṣe nilu won to be ti nwon ni lati lo ṣiṣẹ ni oko ẹru nilu Fernandopo, Azikiwe wa fẹ lati fi owo ti nwon iba fi da iṣe silẹ fun awon enia nwon Universty.

Oloye Akintola so wipe, eni kẹni ti o ba lo dibo fun Hauṣa, ti oluwarẹ ba ti ṣe aṣemaṣe kan, nṣe ni nwon o na ni ogorin bulala.

Oloye Awolowo so wipe nigba gbogbo ti on ba mbọ ni Eko ti on ri Iddo nibiti awon obinrin gbe nta oja, ati oja Ebute-ero, bi ẹgbẹ Action Group ba wole ni Federal on yio tun ibi mejeji na ko, yio gbadun.




# Awon Onirohin Ijoba Nilu Oyinbo



**Awon ti a nwo ninu aworan yi ni awon Onirohin ijoba ile enia dudu ninu ogba afin oba ilu oyinbo. Oruko won ni nwonyi :- O. M. Osman, ara ilẹ Nyasaland, F. O. Okoroji ara agbegbe Ila-orun Nigeria, B. S. K. Banya ara ilu Saro, C. C. Lokko ara ilẹ Ghana ati O. Ogunrinka ara ilu Nigeria.**

**Gbogbo nwon lo lọ kọṣẹ bi a ti nrohin nilu Oyinbo, nwon si ti nko won gẹgẹbi a ti ṣe le so ohun ti a ri ni ojukoju di irohin.**

# Itan Ajapa Ati Ekun

### Apa XII

Lati ọwọ Ẹsọ

**Ẹkun fi iya nlanla jẹ Ajapa nipa ehin erin mejeji na. Ẹkun di ọlọla nla to gba iyi lọdọ ọba, lojojumọ ni Ẹkun ngun ẹṣin kọja lọjude Ajapa bi Ajapa ba si pẹ diẹ ki o to kuro loju ọna, Ẹkun yio gun ẹṣin kọja lọ lori rẹ ti kini kan ko si ni ti idi rẹ yọ jade. Lat gba ti nkan yi ti ṣẹlẹ ọrọ Ajapa ko tan leti ọba mọ ki ẹnikan to le ri ọba, o ni lati kọkọ ri Ẹkun, Ajapa wa di ẹni abuku larin ilu O wa bẹrẹ si ronu kini on le ṣe ti on yio fi gbẹsan lara Ẹkun.**

**Lọjọ kan Ajapa mu ate, o fi si ori igi tente, o ba iho oju agbara wọ baluwẹ inti ọba gbe nyagbe, o lo dakẹ sibẹ. Nigbati o ṣe ọba de lati yagbẹ o bẹrẹ o randi bẹni Ajapa fi ate le loju idi ọba ko si le yagbẹ mọ lati ọjọ na lọ kẹrẹkẹrẹ inu ọba wu, awọn oniṣegun sọ pe jẹdi jẹdi ni, o jẹ egbogi titi inu rẹ kun.**

**Nigbati o ṣe ti ọrọ na ṣe ndi oju iku lọ fun ọba, ti gbogbo ile ọba pa rọrọ Ajapa digbẹrẹ wa sile ọba o ri Ẹkun, o bere wipe on fẹ ri ọba, Ẹkun dahun pe ọba wo, ọba ti inu rẹ wu ti o nfẹ ku teni-tọla.**

**Ajapa kigbe ha kinla, amodi ti o pa baba rẹ (ọba) nuni** ẹjẹ ki nlọ wo na. Ni nwọn ba mu Ajapa lọ siwaju ọba. Nigbana Ẹkun ti pada sẹhin. O wi fun ọba bi ọba le ṣe etutu rẹ, loni-loni ni yio san ti yio si jẹun. Ọba ni ki o sọ ọ, on yio ṣe e. Ajapa ni ki ọba lọ wa ori Ẹkun wa bẹni Ẹkun kanṣoṣo lo wa nilu na. Ọba si ranṣẹ pe Ẹkun o ti fi enia ti yio bẹ lori pamọ soju ọna.

Bi Ẹkun ti wọle ọba alọ rẹ ni ari a ko ri abọ. Lojo na ni ọba ri alafia, oye ti ọba ti gbe fun Ẹkun, Ajapa lo tun pada gbe fun. Bayi ni A'apa tun pada gbayi, o si ri ẹhin Ẹkun o pada di arole ọba.

# Ibinu Ko Da Nkan Suru Ni Baba Iwa

Lati Ọwọ Ẹsọ

Ni ọjọ kan, Ojọjọ nṣe Oduduwa, o wa ranṣẹ si awọn ọmọ rẹ mẹta nwọnyi, Alara Ajero ati Ọrọgun wipe ki wọn sare wa wo on kiakia. Awọn mẹtẹta na ko si sọse, nwọn ba ara wọn lo'na ọna, nwọn si jijọ kẹsẹ wọ Afin baba wọn. Bi nwon ti nwole bẹni Babalawo jan Ọpẹlẹ rẹ mọlẹ nigbana ni Odu ti o mbẹ ni isale iwe yi fu soju ọpọn

Ibinu lo nṣe Awo Alara
Ẹdọ fufu lo nṣe Awo Ajero
Pẹlẹturu lo nṣe Awo Orangun
Awọn mẹtẹta lo nṣe ọmọ Oduduwa
Lọjọ ti a difa fun wọn pe
Nwon ko gbọdọ binu rara
Ki ohun gbogbo le di tiwon.

Babalawo na kilọ fun awon mẹtẹta, o wipe Ha ibinu ko da nkan suru baba iwa agba to ni suru ohun gbogbo lo ni alejo nla kan mbọwa ba won gbe titi oṣu mẹta loni yio ma firan nipa sise ohun ti nwon ko fe sibẹ nwon ko gbodo le jade.

Ko to iwon ojo mẹsan alejo kan de sile Alara o bẹrẹ si finran to bẹ inu bi Alara o le e jade. Nigbati alejo na kuro nibẹ o kori sile Ajero o tun bẹrẹ si se ohun ti Ajero ko fẹ o yo kumọ ti i o lee jade.

Alejo na wa kori sile Ọrọgun bakanna o tun bẹrẹ ṣi huwa ti ko tẹ Ọrọgun lọrun kaka ki Ọrongun binu le jade o tunbọ ko mọra. Nigbati alejo na ri oye pe Ọrangun ko binu, o pe e sinu ile o si fi ohun gbogbo ti o jẹ rere fun.

# Jamba Moto Niwaju Ikorodu

Lojo Satide ojo keji osu yi ni jamba Moto akero, eyiti nwon npe ni Kia-kia bosi meji sele niwon ibuso merin si ilu Ikorodu. Okan ninu awon Moto na nti ona ilu oke bo, ekeji si nti ilu Eko lo sile oke, awon mejeji wa f'ori so arawon niwaju ilu Ikorodu ki o wa wo agbara ę'e enia bi o ti nsan rere nile.

THE CARELESS OMOLANKE AND IMPATIENT DRIVER




E wo aworan yi, ki e ri ise ti Omolanke nse pelu moto nilu Eko.

A gbo wipe enia meta loku lesekese, iya agba kan ati enikan pelu awamoto kan. Enia metala ni a gbo pe o wa ni ile iwosan (Hospital) ni Yaba, enia kan ti o m'ori bo, ni o so wipe "awa maridi nise Olorun" on ko mo bi on ti se yo, nse ni mo kan ba arami gedegbe loto lehin ti jamba na sele. Ise Olorun leyi. Lowo jamba Moto, Oluwa rere gba wa.

## Dr. Nkumah Pada Dele

ACCRA .Nigbati DR. Nkrumah pada de ile awon Aganyin, nibiti o gbe joye Prime Minister fun won, o so larin awon igbimo re wipe, "Mo rope, bibewo ti mo lo be ile Nigeria wo yi, tunbo mu ki irepo ti o mbe ni arin meji ile Ghana ati ile Nigeria tunbo le gboin-gbin.

Nigbati DR. Nkrumah gunle si Accra o so wipe, fun iba ojo mejila ti mo gba nile Nigeria, mo rope ao tun jijo se apero lori oro gbogbo ti a ti jumo ro siwaju sugbon o ye ki nfi ye nyin wipe, lati isisiyi lo ile Ghana ati ile Nigeria ti di okan. Bi ede ko yede kan ba tile wa tele ri, gbogbo re ti pari pata-pata.

Ati wipe lati isisiyi lo awon ile mejeji nwon yi yio ma sise po fun isokan ile Afrika ni apa Iwo-orun

## DOKITA NNAMDI AZIKIWE



Irohin kan wa wipe Olola Azikiwe yio lo soro nipa isele ni agbegbe ile Ariwa ati agbegbe Iwo-orun.

Lojo Monday otunla ni yio de ilu Asaba ti yio si bere ise re.




## Ile Epo Kerosini Fo Ni Apapa

APAPA. Irohin ko to afojuba ni Apapa nigbati ona iho ti epo Karosini ngba fo, ti gbogbo awon enia si ngbe koroba, garawa, korodomu lo gbon epo karosini wa sile ni ofe.

Awon oyinbo to ni epo na nje Esso West Africa Incorporation ti Apapa lo ni adanu na. A gbo wipe asiko na je asiko ekuumi (Iyo). Ekuumi gbe epo ti o da soju omi wo inu ira lo tobe ti a fi gbo wipe awon oku eja po loju omi a si tun gbo wipe, o di oku eran'mi (Oni ati Elegungun) marun ti nwon ri gbe loju omi ito (Canal) Ohun ti a gbo wipe o fa sababi yi ni pe, ide ibiti nwon gbe ri irin ona epo na mo jin sinu nwon si mbe lehin atunse ona epo na titi di isisiyi.

E MA KA IWE
IROHIN
ELETI - OFE
L'OSESE OKUN FUN
IROHIN ALADUN

## Ariyanjiiyan Igi Obi Ati Igi Koko

Li ọjọ kan gbogbo awọn igi oko pẹjọ sile Iroko baba igi, nitoripe, igi Iroko fẹ gbe igi Ayunrẹ ni iyawo. Ni ọjọ ti aisun iyawo ku ọla, ni ẹsẹ awọn igi oko pe, ti olukuluku si bẹrẹ si taka ọla ati iyi rẹ larin awujọ.

KOKO. Igi eso Koko lo kọkọ bọ siwaju o wipe Baba ẹgbẹ, Alaga, ati Ijoko mo ki gbogbo nyin pọ. Ẹnyin na ti mọ wipe, ọrọ gbogbo lori ṣile - agbalagba ti o nfọ ni Kaa ti ko ni owo lọwọ, akọ aja lo ngbo; ko si ẹniti o jẹ fi oju kan owo ki o salọ. Kurumọ nwa owo, Aganyin nwa, ẹniti o ni owo na paa tunbọ nwa, bẹni awọn Agbẹ nwa a pẹlu.

Paapa bi mo ti gbayi to ko si igi kan ti nwọn ko le ge lulẹ nitori mi, nitori ki o ma ba di mi lọwọ. Baba ẹgbẹ ati Alaga si mọ bẹ.

OBI. Igi obi bọ si agbo, o ni Baba-ẹgbẹ, Alaga, ati Ijoko, gbogbo nyin ni mo ki, emi ko fi ara mọ ọrọ pala-pala ti igi Koko ti nsọ lati oni yi wa. A ha le wipe nitori aiye daiye oyinbo, ki a maṣe mọ agba ni agba. Tabi ẹnyin ko gbọ wipe igi gbogbo lo nso owo ọtọ ni ti obi. Eyiti o si fẹ fara jọ obi, lo ya abidun.

Kinla, iwọ Koko ẹnu ọjọ mẹta yi! nitoripe awọn agba fun ọ laye lati sọrọ, o ŝi bẹrẹ si la bata ọrọ mọ wa lara, o ma gọ diẹ o. Nigbati agbado koiti de aiye, ohun kan dandan ni adiẹ njẹ.

Jẹki nwi fun ọ, bi o ti wa ni Liki, bakanna lo wa ni Gbanja. Bi iwọ ba wulo to gẹgẹbi o ti ṣe irohin ara rẹ yi iwọ ko gbọ wipe igi gbogbo lo nso owo oto niti obi. O di gba melo ti nwon lo fi ọ yangan nile ana ri? tabi nwọn ha le fi ọ ṣe alejo bi? Haba ẹ lọ rẹ ara nyin nile, ki olukuluku si mọ babu ara rẹ.

ỌPẸ. Bi igi Obi ti panumọ bẹni igi Ọpẹ dide fuya, o wipe Alaga ati Ijoko, Kabiyesi o, mo rope, bi nko ba sọrọ rara boya nwọn le rope ẹru ija lo mba mi. Ko nṣe iwa mi lati ma gberaga ati Koko ati Obi emi ko nṣe ẹgbẹ wọn. Emi wulo ju awọn mejeji ti o sọrọ gbẹhin, gbọ bi awọn enia ti ti nki mi wipe Ọpẹ fi ori ṣowo, o f'di ṣe okun, o fi agbede meji ṣe kiki ẹmu.

Bi enia ko ri mi ko le se obẹ, epo mi ni nwọn fi nṣegbogi ewe mi nwọn fi mbo ile melo ni ki nka melo ni ki nsọ. Nigbati Ọpẹ nsọrọ awọn miran tun nfẹ sọrọ, ṣugbọn Alaga sọ pe asiko lati jẹun ti to. Ibẹ ni ọro ba pari si.

## Ipania Ti Kari Aiye

KANO. Kakiri ni a ngbọ irohin nibi ati lọhun wipe nwọn ri oku enia kan ninu igbo, yala ki nwon ge e ni apa tabi ẹsẹ tabi ki eya ara rẹ ma pe kini ẹredi gbogbo iṣẹ buburu nwonyi? Nilẹ Isalẹ Ọya ni a gbo pe nwon nsaba hu iru iwa bẹ ṣugbon aṣa na dẹ ti gunlẹ si Oke-Ọya nisisiyi.

Nigboro Kano ni a ti gbo wipe nwon iri oku omo ojo mẹta kan ninu ogodo ti nwon ti ge diẹ kuro lara eya ara rẹ.

Ọkunrin kan ti o ngbe tosi ibẹ pẹlu aya rẹ ni owo olopa tẹ, nwon si nwadi lowo, ṣugbon nwon ko fi awon tokotaya yi lorun silẹ.

AJALA TUN BẸRẸ IRIN-AJO

**Ọgbeni Ọlabisi Ajala ọmọ bibi inu Alhaji Ajala nilu Eko nibio ti pada de ilu Oyinbo o si tun bere irin** ajo rẹ arin yi aiye ka lori ekeji.

O fẹ de ilu Arabu ilu Chaina ati ilẹ India ki o si foju kan awon Olotu ilu na.

## Oloye Kola Balogun



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Oloye Kola Balogun okan ninu awon ti o fẹ fi tulasi yo Asikiwe kuro ni aṣiwaju, a ẹhinwa-asẹhinbo on na ni nwon yo kuro lẹgbẹ. Nigbẹhin o tun nfẹ pada sinu ẹgbẹ ti a ti yo kuro, ṣugbon nwon ko gba a mo.





# Onisowo Ohun Isere Omode

**Coopexim**

COOPERATIVE COMPANY FOR FOREIGN TRADE LTD.

WARSZAWA, ZURAWIA 4, POLAND.

TELEGRAMS: COPEX - WARSZAWA.

Ohun ti a nta niwọnyi :- Bebi (Dolls) ati awọn ohun iṣere ọmọde, Adamọdi igi-ọdun Keresimesi, awọn ohun ọṣọ-ara ati ọṣọ-ile, Orişirişi Brọşi (Brushware) Orişirisi ohun ipẹja, Şuku ati Apẹrẹ lorişirişi, awọn nkan ti a fi irin ṣe. Orişirişi awọn ohun ti a fi nya aworan, Orişirişi aṣọ ẹwu t'ọkunrin t'obinrin awọn nkan ti a nko ẹfọ ati eso pamọsi, Ẹgbogi mimu ati pipara, Aṣọ Bulankiti ati Damasi.

A NFẸ AṢOJU NIBIGBOGBO

# NISISIYI !

FUN IGBA AKOKO NILE NIGERIA ...

AWON ONIṢOWO

## THE NIGERIAN GAS CORPORATION LTD.

YIO MA ṢE

ETO GBIGBE IDANA GAS SINU ILE LATI MAFI DANA

Ale fi Gas pelu Meter re sinu ile ti a ngbe. Koni agbekiri. Ko si ni ṣalai

muna wa nigba kan. Ko lewu, o rorun, lilo re din inawo ku.

ẸNYIN KỌLEKỌLE ONILE ATI ẸNIKẸNI TI O BA FẸ LILO RẸ KI

O KỌWE FUN ALAYE KIKUN LỌDỌ :-

## NIGERIAN GAS CORPORATION LTD.

2, WAPINU AVENUE, P.M. BAG 1040 APAPA TELPHONE 55295.

Iye owo re ati gbogbo alaye nipa re ni ao se fun yin lofe.


nwọn ko ri ẹbọ abamọ ṣe.

Ọdaran na kebosi nigbati awọn ọlọpa yọ okuta ti o fi pa Taiwo Dina jade, a gbọ pe okuta na tobi, lọjọ aisun ọdun titun lo ṣe jamba na.

Ọkunrin kan jẹri wipe, apania yi lo ni okuta na, nitoripe' lasiko na David Lucas ti ju okuta yi lu on ati iyawo on ri. Ejọ na nlọ si kotu giga ti awọn arufin.

## OKe Ilu Kamaru Binu

BUEA. Irohin kan wa lati ilu Kamaru (Cameroon) wipe nigbati oke giga nla kan ti o wa nilu na bere si tu omi jade ni awọn ara Abule meji to wa nitosi oke na ba nko jade kuro ni Abule wọn fun iberu boya o le ṣe jamba.

Awọn Abule to nsa asala fun emi wọn na ni awọn ara Abule Isoka ati Ekona. Ṣugbọn nigbati okiki na kan de etigbọ awọn ọlọpa, nwọn lọ be ibẹ wo, nwọn si sọ fun awọn enia na wipe ko si ewu fun wọn rara nitorina ki wọn maṣe beru.



S. L. AKINTỌLA

Eyi jẹ ọrọ ti Oloye Akintọla sọ ninu ile igbimọ Apapọ wipe "Oke ilu Kamaru ko fẹ ya kuro lara Nigeria".


ARA-O-LIN - IPARA ATATA




ARA-O-LIN je [illegible] O tayo gbogbo irufe egbogi [illegible] egbedidun, aran- [illegible] arinka-inu-egun iti apa [illegible] ooru-agbari, ikun-didimu, [illegible] Nitori [illegible] ni "ATA". Ibo npe e ni "OSU" [illegible] "KOROKONU". Dan igo kan wo ni 1s. 6d. [illegible] nl.

The Egba Trading Arandan Stores,
18 Denton Bridge St. P. O. Box 2, Ebute-Metta.


## Mase Bi Asiwere!

IKEJA. Ọkunrin apania kan ti orukọ re nje David Lucas, eniti a gbọ wipe on lo ṣe sababi iku ti o pa ọmọ ilewe Olu Iwa College kan ti orukọ re nje Taiwo Dina, ni nwọ- nse ejọ re lọwọ ninu kotu Ikeja, o kigbe wipe ki Ọlọrun wa pelu eniti o ko nkan yi wa!

Adajọ sọ fun ọkunrin na wipe ko nṣe akoko yi ni iwọ y'o dibọn pe, o ko mọwo, mẹsẹ. Owe awọn agbalagba kan so pe, Oṣe lo ngiwaju ẹkun, abamọ a si gbẹhin ọrọ, gbogbo awọn Ọtọkun ilu pejọ.

## Orin Fun Orisa Dada.

Dada Awuru ọmọba, ma ma loko l'Oke-odan, ko ma f'ẹsẹ ko janin-janin. Dada Awuru o, onitobi wura, penpe.

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street Lagos P. O. Box 467 Phone 23370